**3.** Nitorina ki nwọn mã sin Oluwa Ile yi.

فَلْيَعْبُدُوا رَبَّ هَٰذَا الْبَيْتِ ﴿٣﴾

**4.** Ẹniti O nfun wọn ni onjẹ jẹ lakoko ebi ti O si nfi wọn laiyabalẹ̀ ni akoko ipaiya.

الَّذِي أَطْعَمَهُم مِّن جُوعٍ وَآمَنَهُم مِّنْ خَوْفٍ ﴿٤﴾

## *(107) Suratul - Mã'ũn*

## سُورَةُ الْمَاعُون

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Njẹ o kò ri ẹniti o npe ẹsan nirọ?

أَرَأَيْتَ الَّذِي يُكَذِّبُ بِالدِّينِ ﴿١﴾

**2.** On ni ẹniti nle ọmọorukan.

فَذَٰلِكَ الَّذِي يَدُعُّ الْيَتِيمَ ﴿٢﴾

**3.** Atipe kò gbiyanju lati bọ alaini.

وَلَا يَحُضُّ عَلَىٰ طَعَامِ الْمِسْكِينِ ﴿٣﴾

**4.** Egbe ki o mã ba awọn akirun.

فَوَيْلٌ لِّلْمُصَلِّينَ ﴿٤﴾

**5.** Awọn ni awọn olusọ ọkàn nu kuro nibi irun wọn.

الَّذِينَ هُمْ عَن صَلَاتِهِمْ سَاهُونَ ﴿٥﴾

**6.** Awọn na ni alaṣehan (karimi).

الَّذِينَ هُمْ يُرَاءُونَ ﴿٦﴾

**7.** Nwọn a si mã kọ̀ nkan ajọlò (gẹgẹbi-koroba-abẹrẹ-abọ-) fun awọn enia. (Mã'ũna).

وَيَمْنَعُونَ الْمَاعُونَ ﴿٧﴾

## *(108) Suratul - Kaosara*

## سُورَةُ الْكَوْثَرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Dajudaju Awa ti fun ọ ni õre ti o pọ (Kaosari).

إِنَّا أَعْطَيْنَاكَ الْكَوْثَرَ ﴿١﴾

**2.** Nitorina kirun fun Oluwa rẹ, ki o si gun ẹran (ileya).

فَصَلِّ لِرَبِّكَ وَانْحَرْ ﴿٢﴾